**Lakaye Ọrọ**

NIGBANA ni mo wo gbogbo Iṣẹ Ọlọrun, pe enia ko le ridi iṣẹ ti a nṣe labẹ ọrun nitoripe bi enia tilẹ gbiyanju ati wadi rẹ, aibesibe ki yio le ri i, ati pẹlupẹlu bi ọlọgbọn enia rẹ lati wadi rẹ, aibẹ ki yio le ridi rẹ.

# Irohin Yoruba

NO. 832. May 17-May 23, 1961. KOBO MEJI (2D)




Dara fun Ẹjẹ Ọmọde, Agba ati Aboyun

O wa fun tita kakiri Ile-egbogi

# ADEGBENRO DI ẸKẸRIN ẸGBA

ABẸOKUTA.

**IROHIN ko to afojuba ni aṣeyẹ oye Ẹkẹrin Ẹgba (Abẹokuta) ti awọn afọbajẹ fi Alhadji D. S. Adegbenro, Minista Alamojuto Eto Ijọba Ibilẹ Ipinlẹ Iwọ-Orun jẹ lẹnulọlọyi ni Abẹokuta. Ọlọla Ọba Alaiyeluwa Ladapọ AdemọlaKeji si sọ bi Oloye na ti ṣe jẹ akikanju enia atiọmọluwabi si ati bi o si ti ṣe wulo pupọ fun ogo atiigbega ilu Ẹgba, o si wure fun un.**

Ẹsẹ awọn enia pataki pataki ni o pe ṣoṣo si ibi aṣeyẹ na; awọn bi Oloye S. L. Akintola, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ati Oloye Iyaafin Faderera Akintọla; Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Aṣiwaju Ẹgbẹ Alatako Apapọ Ijọba Naijiria ati Iyaafin Oloye H. I. D. Awolọwọ, Alhaji Oloye D. S. Adegbenro si fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣeye ọjọ na lọrun titi di ọgọnjọ oru. O si dupẹ lọwọ wọn gidigidi.



NINU aworan yi Oloye Adegbenro ni o nfi ẹrọ gbohungbohun dupẹ lọwọ awọn alabaṣeyẹ rẹ.

## Ọkunrin kan sọ pe on ko le ṣalaimu Ọti bọlugi

EKO.

LARIN igbati Ọgbẹni Adefarasin, Adajọ kotu kekere, Yaba ngbọ ẹjọ ẹsun ti awọn ọlọpa fi awọn ọkunrin mọkandilogun kan ninu Ẹgbẹ Oloriṣa Ẹlẹgba, Abule Ilogbo, Ebute-Mẹtta sun si Kotu na, ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi ni Ọgbẹni Adewale Thompson ti iṣe agbejọro awọn ọdaran na, fi ibere kan si iwaju Johnson Etete, ẹlẹri Ijọba ninu ẹjọ na, ti o ti ngbe nomba 5, Shomore Street, Ilogbo, Ebute Mẹtta lati bi ọdun marun sẹhin pe, "Njẹ iwọ ko ti fi ponun mẹdogun (£15) ati ponun mẹdogbọn (£25) tanran si Kotu ni igba meji ri, nitori ẹsun pe, o ta ọti bọlugi?"

Etete si fesi wipe, lotitọ ni on fi owo tanran si Kotu ni igba mejeji, ṣugbọn nitori ẹsun wipe on mu ọti bọlugi ni, ki iṣe nitori pe on ta ọti bọlugi gbogbo enia si bu-ṣẹrin, nigbati o fi Oyinbo apalapulu sọ wipe, "on ko ti i fi ọti bọlugi mimu silẹ, bi on ba si tun mu u lọla, ki ọlọpa wa mu on" (I never left drinking illicit gin. If I drink am tomorrow,-make police come catch me).

Ṣiwaju eyi ni Ẹlẹri Ijọba na ti jẹri tako awọn ọdaran na pe, awọn ni alakoso eto iborisa na, ọmọ Ẹgbẹ Ẹlẹgba si ni wọn. Larin ọdun Ẹlẹgba, nwọn nkilọ fun awọn enia pe ki wọn maṣe jade lati agogo mẹsan alẹ titi di igbati ilẹ ba mọ.

Atipe, larin igbati nwọn nṣe ọdun Ẹlẹgba na ni oṣu ti o kọja yi, nwọn ṣigun lọ bo ile obirin kan ti orukọ rẹ njẹ Christianah Okoh, nwọn si ba ohun-ini rẹ jẹ. Etete tun sọ siwaju pe, gbogbo awọn enia ti o ba ti jẹ alejo ni awọn Ẹgbẹ Ẹlẹgba na ma a nsọ pe ki nwọn da owo ni akoko ọdun Ẹlẹgba, on tilẹ da ṣile mẹrin abọ (4s. 6d.) fun awọn enia na ri.

## Enia marun farapa ninu ijamba mọto

IBADAN-ỌYỌ.

BI mọto akẹru kan ti sojude ni iyana Ibadan si Ọyọ ni Muniratu Raimi, ọmọ oṣu mejidinlogoji si ku lẹsẹkanna ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi. Ọgbẹni Amusa Agboola ti o nwa mọto na ati awọn ero inu mọto na marun si farapa pupọ.

# Ọlọpa ba oku baba, iya ati ọmọ loju ọna

ISAO-ILỌRIN.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni awọn ọlọpa ri oku tọkọtaya 'kan, Yisa Yẹkinni ati Salamọtu Yẹkinni ati ọmọdekunrin, ọmọ wọn ni ọna Isao lẹba Ilọrin; ti ẹnikan ti ṣa wọn pa sibẹ.

Awọn ọlọpa si sọ pe Yisa Yẹkinni ti ṣe ileri ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ karun oṣu yi lati ṣa aya rẹ na lọbẹ pa, ati pe o si sọ fun awọn pe ọkunrin kan wa s'ọdọ aya on ni arọ ọjọ Aiku ti iṣe ọgbọnjọ oṣu ti o kọja yi nigbati on de lati oko ti on ti lo.

Yẹkinni si tun sọ fun awọn ọlọpa pe, nigbati on si bi aya on lere pe tani ọkunrin na nṣe? Nṣe ni o dapara fun on pe, iwọ ṣe bi emi wa fun iwọ nikan ni. O si tun ṣe alaye fun awọn ọlọpa pe, ọmọ kekere ti obirin na ni on bi, fun on ko jọ on rara ṣugbọn ọkunrin alejo na ni o jọ lọpọlọpọ.

Awọn ọlọpa si nṣe iwadi nipa ọran na.

## Obirin kan gbe majele fun ọkọ rẹ jẹ

ILỌRIN.

O YA ọpọlọpọ awọn enia ti o wa si Kotu Kekere Ilorin lẹnu ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi nigbati ọdaran abilekọ kan Alimot. Dekeje ti awọn ọlọpa mba ṣe ẹjọ apania pe, o pa Hassan Dare ọkọ rẹ, sọ fun Adajọ pe, on ni on pa a lotitọ.

Ọdaran na si ṣe alaye fun Adajọ pe idi ti on fi pa a nipe ọkọ on na ni o pa Liadi Kadiri, akọbi on fi ṣe oogun.

O ni, ni ọdun ti o kọja yi ni ọkọ on ni ki ọmọ on na sin on kalọ si oko ṣugbọn alọ ọmọ on ni on ri, on ko si ri abọ rẹ. O si tun sọ fun Adajọ pẹlu omije loju rẹ pe nigbati on si bere ọmọ na, esi ti o fun on ni pe o wa ni oko pẹlu awọn ẹgbẹ rẹ. O ni lati igba na ni on ko si ri abọ rẹ titi di oni.

**ATOKA I WO**

IWUYE Oloye Shọnibarẹ ni oju ewe kẹfa ati keje.

# Iwuye Shọnibarẹ dun, o larinrin

IJẸBU ODE.

IROHIN ko to afojuba ni ti aṣeyẹ iwuye Oloye S. O. Shọnibarẹ, Alakoso Agba ile iṣẹ itẹwe "Amalgamated Press Ltd." l'Eko, ti nwọn ṣe ni Afin Awujalẹ Ijẹbu Ode, ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi.

Iwuye na ku nkan bi ọjọ marun ni awọn enia ti nrọ wọ ilu Ijẹbu Ode. Nigbati ọjọ na si ku ọla, irọkẹkẹ na ti pọju, awọn to de lati oke Ọya, Oke Okun, Ibadan, Abẹokuta, Eko ati ọpọlọpọ ilu ni Ipinlẹ Iwọ-Orun ko niye.

Nwọn ṣe aisun mọju ni. Gbara bi ilẹ ọjọ na si ti ngmọ ni awọn enia ti nya lọ si Afin Ọba, Lati owurọ ọjọ titi ilẹ fi ṣu awọn enia fi njo, ti nwọn si nyọ.

Iwuye na dun, o larinrin. Oye yio mọ'ri o.

**Wo oju ewe kẹfa ati ekeje fun aworan iwuye na.**

## Lemọmu Atiku jalaisi l'Eko

GBOGBO awọn Ijọ Alalukurani l'Eko ati agbegbe rẹ lo wa sibi isinku Alfa Atiku Amọdu, Lemọmu Mọṣalaṣi Atini l'Eko ti o jalaisi ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu ti o kọja yi ni ile rẹ nigbati o di ẹni adọrun ọdun.

Isinku Lemọmu na dun pupọ, awọn enia patakipataki lo si wa si ibẹ. Lemọmu-Agba Shekoni ti Ijọ Alalukurani lo ṣe eto isin ọjọ na. Nwọn si sin oku na si Itẹ Ikoyi.

Ninu awọn ọmọ ati awọn ọmọ-ọmọ ologbe na ni Ọgbẹni Ganiu M. Atiku, ọga ile iṣẹ "Nigeria Ports Authority", ni ilu Pọta (Port Harcourt) ati Rabiu Agunbiade ti ile iṣẹ "Palm Line" l'Eko.

## Ile Mcbee gba Ife-ẹyẹ ni Ikogosi

IKOGOSI, EKITI.

AWỌN ọmọ ile iwe Ijọ Onitẹbọmi (Baptist Secondary Modern School) ni Ikogosi Ekiti ṣe ere onile-j'ile ikini (inter-house sports) ni ọgba ile iwe na ni irọlẹ ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu ti o kọja yi. Ere na dun, o larinrin, awọn enia si pọ pupọ ti nwọn wa woran.

Gbogbo enia ni nwọn ho ge e nigbati Ebenezer Akintujoye kọ bi mọnamọna lẹgbẹ awọn ẹlẹgbẹ rẹ lati gba ipo kini ninu ere sisa ọlọgọrun ọpa. Ni ipari, ile McBee, ti Ọgbẹni Adefọlaju jẹ aladari rẹ ni o ṣe ipo kini wọn si gba Ife-ẹyẹ ti a npe ni "Titilayọ Cup".

Ọgbẹni James Amigun, alaga ọjọ na ti i ṣe ọga ile itawe "Titilayọ Bookshop" ni Ilesha tun fi ẹbun ẹwu agbabọlu mejila ta ile ẹkọ na ni ọrẹ. A nfi si iranti gbogbo enia pe Ọgbẹni James Amigun yi na ni o fi Ife-ẹyẹ ti a npe ni "Titilayọ Cup" yi ta ile ẹkọ kan yi na lọrẹ ni ọdun ti o kọja.

Ni ipari, Ọgbẹni P. B. Ogundana ti o jẹ olori ile ẹkọ na dupẹ lọwọ gbogbo awọn ti o wa woran. O si dupẹ lọwọ Ọgbẹni Amigun fun ifẹ rẹ si ile ẹkọ na.

# Ijọ Ahmadiyya fi'pilẹ Mọṣalaṣi Ikorodu lelẹ



IKORODU.

**EṢẸ gbogbo awọn Ijọ Ahmadiyya l'Eko, Abẹokuta, Ibadan ati ibomiran lo pe sibi aṣeyẹ ti ifi ipilẹ Mọṣalaṣi Ikorodu lelẹ ni ọjọ Aiku ti i ṣe ọgbọnjọ oṣu ti o kọja yi.**

Ọba Alaiyeluwa S. O. Ladega, Ayangbunrin Ikorodu ni Alaga ni ọjọ na. Ninu ọrọ iṣiri ti o sọ Ọba Ladega ki gbogbo awọn Musulumi, paapa awọn Ijọ Ahmadiyya fun ifọwọsowọpọ wọn ati aayan wọn fun ilọsiwaju ati anfani ilu.

Lẹhin eyi ni Alhaji Ashafa B. Tijani, Lemọmu Agba Ijọ Ahmadiyya l'Eko sọrọ. O dupẹ lọwọ Ọba Ladega fun ifẹ ti o lo si awọn ijọ na, o si ṣe adura fun anfani ilu Ikorodu ati fun gbogbo ilu Naijiria.

Ṣiwaju gbogbo eyi, ki eto ifipilẹ Mọṣalaṣi na lelẹ to bẹrẹ, gbogbo enia to wa sibi aṣeyẹ na dide duro fun adura pataki ti Alhaji A. L. S. Akodu, Aṣiwaju oniwasu Ahmadiyya na ṣe.

Ninu awọn ti o wa sibi aṣeyẹ na ni Ọlọla L. J. Dosunmu, Aṣoju ilu Eko ninu Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria ti i si iṣe 'Gbakeji OloriIjọ Ahmadiyya.

**AWỌRAN** oke yi ni ti igbati nwọn ngbadura ki eto aṣeyẹ ọjọ na to bẹrẹ. Lati owo osi awọn ti nwọn wa ni iwaju ni Ọgbẹni R. A. Ṣolaja, Alhaji A. L. S. Akodu, Alhaji Ashafa B. Tijani, Ọba Ladega, Ọlọla L. J. Dosunmu ati Alhaji Amọdu Tijani.




FERESE ATATA NI NITORI:

Ayọ t'o gbe jingi rẹ duro jẹ k'o rọrun lati ṣi.
Ọda t'o ba fẹ l'o le fi kun u.
Orisi meji l'opo rẹ: onirin ati ayọ. Onirin lagbara; alayọ ndan yọyọ.
O ṣe ṣi diẹ; o ṣe ṣi pupọ fun atẹgun
O rọrun lati fi kọ'le.
Gbogbo ẹni t'o lo o ni Iwọ Orun Afrika jẹri pe o dara.

NACO SUN SASH

FERESE ALATẸGUN TI A ṢE NI NIGERIA

VIVIAN, YOUNGER & BOND LTD.

LAGOS IBADAN PORT HARCOURT KANO KADUNA ENUGU.



DA INU RIRUN DURO

Nigbati o ba ni irora ninu ikun rẹ, ohun ti o nfa idi rẹ nigbagbogbo ni pe omiro ti pọju nibẹ....Omiro yi ni o nfa arun-inu, inu-kikan-ni ati airi-igbẹ-ya
Ṣa ti mu egbogi Phillips' "Milk of Magnesia" diẹ . . . . yio si ko rirogun omiro na kuro, a si le irora na lọ werewere....Yio fun okun-inu lagbara lati ti gbogbo nkan ti o nfa irora na jade kuro lara.
Ko lewu. e roun lati lo, o si tu ni lara.

'MILK OF MAGNESIA'

AWỌN TI O NṢE E NI

PHILLIPS




O DARA FUN GBOGBO ẸBI

# KADARA ẸDA (19)

## Lati ọwọ M. A. Akinbọade, Ibadan)

NWỌN ni ọrọ asọti l'o nję kini ana. Nipa ibiti a ba ọrọ wa de, a kiyesi bayi wipe: Ọmọ ti o ba wa s'aiye ni ọjọ kẹta ọsẹ ti a npe ni "Tuesday" (ọjọ Iṣẹgun) yio kun fun okun (agbara)) ti ọkan ati ti ara, bakanna ni yio si jẹ enia ti o ni agidi ati oninu fuufuu.

O dọwọ iru awọn enia bayi lati lo okun ti nwọn ni ni ọna rere. Oju le ma a kan wọn pupọ lati jẹ ohun ti nwọn fẹ jẹ tabi ni ohun ti nwọn fẹ ni. Iṣọra ni ẹbọ igbesi aiye wọn!

Ẹniti a ba bi ni ọjọ kẹrin ọsẹ ti a npe ni "Wednesday" (ọjọ 'Ru) yio ni iṣẹ pupọ pẹlu irin ajo, iwe kikọ tabi riranṣẹ si okeere tabi riri iwe tabi iṣẹ riran gba. Boya iru enia bẹ ẹ fẹran ọrọ asọju, paapa bi a ba bi i labẹ irawọ ti o njọba ọjọ yi gan an.

### OLOKIKI, ALAANU

Ọmọ ọjọ karun ọsẹ "Thursday" (ọjọ Ọjọbọ) a ma a jẹ olokiki enia, olufọkansin ati alaanu. Ọpọlọpọ iru awọn enia bẹ ẹ ni nwọn ndi olowo ati ọlọrọ laiye, nwọn a si ma a gbooro pupọ paapajulọ bi a ba bi wọn labẹ Irawọ ti o njọba ọjọ yi gan an.

Awọn ọmọ ọjọ kẹfa ọsẹ ti a npe ni ọjọ Jimọ (ọjọ Eti) jasi ẹniti o wa si aiye lati fẹran awọn enia ati lati ri ifẹran gba pada lọwọ wọn.

Nikẹhin awọn ọmọ ọjọ keje ọsẹ ti a npe ni "Satide" (ọjọ Abamẹta) kadi gbogbo awọn nkan wọnyi nilẹ nipa jijẹ enia ti o ni ifẹ si jija fun ki ohun gbogbo ti a ti gbin nipa ero, ọrọ ati iwa wa le so eso rere fun igbadun ọmọ enia.

### ỌRUN ATI AIYE

Ọjọ yi ati Irawọ ti njọba rẹ sopọ mọ ọrun ati aiye ẹmi ti onikaluku wa yio jẹ ẹmi onikaluku wa yio jẹ lẹhin wahala ile aiye yi.

Gẹgẹbi mo ti ṣe alaye lẹkan, a ko le ni aye to lati fọ gbogbo ọrọ yi si wẹwẹ, ṣugbọn bi a ba ri ẹnikẹni ti o ni ibere, ẹ le kọwe si mi ni "P.O. Box 108, Ibadan".

Ki ẹnikẹni ti o ba kọwe maṣe gbagbe lati fi sitampu sinu iwe rẹ fun esi o.

### AGBARA ATI AṢẸ

Wayi o, nigbati Ọlọrun da aye, o pe IMỌLẸ ni ọsan ati okunkun ni oru. Ni itumọ ti ẹmi, a le sọ bayi pe akoko iṣẹ (wahala) ati akoko isimi, tabi akoko ireti ati akoko imuṣẹ.

Awọn ọjọ mejeje ti o wa laarin ọsẹ jasi agbara nla-nla meje. Bi Ọlọrun ti nṣẹda awọn nkan kọọkan ni ọjọ kọọkan, bẹni iru agbara ati aṣẹ ọjọ na ngni apẹrẹ lori awọn ohun ti a da na.

Awọn agbara nla ati aṣẹ wọnyi jẹ ti Ọrun ati ti Ọlọrun tika ara Rẹ.

### IWADI IJINLẸ

Laipẹ ẹwẹ, nigbati awọn akẹkọ ohun ijinlẹ ṣe orisirisi akiyesi ati iwadijinlẹ nipa aiye ti a wa ati igbesi aiye ẹda, nwọn kiyesi wipe dajudaju awọn Irawọ, tabi aiye miran gbogbo ti Ọlọrun da, ko ṣai ni aṣẹ ati agbara lori kadara enia.



M. A. AKINBỌADE

* * *

Bi kadara ba tilẹ wa rara, a le sọ wipe nigba dida aiye gan an ni a ti da kadara ẹda ti a si ti fi si abẹ awọn ofin ati eto wọnyi gẹgẹbi akiyesi ati iwadi awọn akẹkọ ijinlẹ wọnyi lati ẹgbẹgbẹrun ọdun sẹhin.

Nitoripe a jẹ ohun ti a jẹ ni a fi wa ni iru ipo ti a wa yi. Nitoripe a wa ni iru ipo yi ni a fi jẹ ohun ti a jẹ.

### OFIN IṢẸDA

A ti kuna lati jẹ ohun ti a fẹ jẹ nitoripe a ti ṣe aṣiṣe kan, tabi a ti ṣẹ si ofin iṣẹda kan, a ṣe aṣiṣe tabi ṣẹ si ofin iṣẹda na nitoripe bi a ti da wa ko jẹki a le ṣe nkan miran.

Mo nireti pe ẹ ntẹle mi bi a ti nbọ yi ati wipe ẹ nkiyesi bi igbesi aiye ẹda ti dabi apẹrẹ, eyiti a hun pọ mọ ara wọn.

Bi a ba tilẹ ronu jinlẹ daradara, ko yẹ ki a jiyan rara nipa wipe irawọ ti o njọba onikaluku ko ri bakanna.

### AGBARA IRAWỌ

Boba jẹ pe ko si agbara orisirisi Irawọ lori awa ẹda ni, bakanna ni gbogbo wa iba ri patapata, nitoripe ọkunrin kanṣoṣo ati obinrin kanṣoṣo ni Ọlọrun da, lati ara wọn ni gbogbo ẹda alaaye si ti jade.

Bawo lo ti wa jẹ ti iyatọ fi wa laarin ẹda?

Njẹ, ẹ ko ri i bayi wipe ọna kanna ti a le gba ṣe alaye kadara ẹda ni nipa ẹkọ ijinlẹ.

Nikadi eyi ni a kiyesi i wipe hihun gẹgẹbi agbọn ni a hun kadara ẹda lati ọwọ awọn Irawọ. Nigbati a ba si tubọ nba ọrọ wa lọ yio tubọ ma a ye nyin siwaju.

Alafia fun nyin.

Ẹ ma polowo
ọja sinu iwe
IROHIN
YORUBA

Ki ọpa-ẹhin le
tọ-rọrọ ki
tapa-titan si
lagbara dada
FUN ỌMỌ
RẸ NI




OSTERMILK

Ile iṣẹ egbogi Glaxo Laboratories Ltd., Greenford, England ni o nṣe e

Awọn alagbata rẹ ni GLAXO-ALLENBURYS (NIGERIA) LTD. P.M.B. 2610, Lagos ati bẹbẹ ni ABA ati KANO .

**ỌRỌ AKEWI : Lati ọwọ ỌMỌ-ỌBA AKIBU ALARAPE, IBADAN**

# ALUBARIKA L'OJU (17)

OLỌTU, karaole o! gẹgẹbi asọti ọrọ wa nigbati Olori awọn ẹmẹwa ọba bere ọrọ yi tan, Iya Ẹlẹha na si dahun wipe, "awa ko mọ ohunkohun nipa Mofoluwasọ nisisiyi, ṣugbọn igbagbọ ti emi iya wọn ni wipe, ni agbara Ọlọrun, a o tun ri ara wa pelu ayọ gẹgẹbi awa mẹta yi tiṣe ri ara wa loni yi."

Lẹhin eyi ni olori ẹmẹwa ọba na wa a kọja lọ sinu kaa ọba, o si ṣe alaye gbogbo nkan ti o ṣẹlẹ na fun un lẹsẹsẹsẹ. Ọba si sọ fun un wipe ki o kesi awọn enia na pe ki nwọn wa si iwaju on lati gbọ bawo ni ọrọ wọn na ti ṣe ri bẹ ẹ; wọn si ṣe bẹ ẹ. bẹ ẹ.

### AWỌN ẸBI ỌBA

Ṣugbọn bi nwọn ti yọ ni ọkankan ni Ọba ti ri wọn, ti o si ti mọ gbogbo wọn daradara, eyi jẹ iyalẹnu nla fun ọba lati ri i wipe, iya on pẹlu awọn aburo on mejeji ną ni wọnyi.

Bayi ni gbogbo wọn ṣe de iwaju ọba na, ọba si bere lọwọ wọn pe, bawo ni idi ọrọ wọn na ti jẹ ti o fi ri bẹ ẹ? Iya Ẹlẹha yi si tun ṣe gbogbo alaye ọrọ na lẹsẹ-ẹsẹ fun ọba.

Ọba si dahun wipe "ko buru." Lẹhin eyi ni ọba na ba paṣẹ wipe ki awọn iranṣẹ on lọ pese ibugbe



AKIBU ALARAPE

* * *

nla kan ti o ba dara fun awọn alejo na ki nwọn si fi wọn wọ si bẹ.

Gbogbo bi nwọn ti jijọ mba ara wọn sọrọ yi, nwọn ko ri oju ọba na rara nitoripe ni inu awẹrẹ ni ọba na paapa ti nsọrọ ti o si ti nwo wọn. Bayi ni nwọn ba pese ile nla kan fun awọn alejo na ti nwọn si nṣe itọju wọn gẹgẹ bi o ti tọ ati bi o ti yẹ.

### IBERE ATI ALAYE

Lẹhin eyi ni ọba na wa kesi Baba — onikẹkẹ ẹlẹsin ti o gbe ẹlẹha na wa wipe, "bawo ni gbogbo ọrọ na ti jẹ o?" Baba-onikẹkẹ-ẹlẹṣin na si ṣe iwọn iba alaye ti o mọ nipa ọran ẹlẹha na.

Ọba si bere pe, "tabi iyawo nyin ni?" Baba na si sọ wipe: "Rara o! nṣe ni anu rẹ kan ṣe mi ti mo fi gbe e sinu kẹkẹ lati gbe e wa si arin ilu."

Ọba si tun bere wipe, njẹ nisisiyi, o dabiẹnipe, lẹhin ti Iya ẹlẹha na ati awọn ọmọ rẹ ti ri ara wọn tan yi, njẹ ipinya ko ni de si arin nyin baun?" Baba na si dahun wipe, "bi eyi ba ri be ẹ, idunnu nla ni yio jẹ fun mi, nitoripe, mo ranti wipe, ni ọjọ ti mo ri ẹlẹha na, nṣe ni o kun fun ibanujẹ, nigbana ni mo ṣe ipinnu ninu ọkan mi lati le ran an lọwọ pẹlu ero wipe, boya nipa iranlọwọ ti mo ba ṣe fun un ni yio fi ri idunnu dipo ibanujẹ ti o gba ọkan rẹ kan ni ọjọ na.

### ADURA MI GBA

"Ṣugbọn laiṣe ani-ani, inu mi dun wipe, Ọlọrun gba adura mi na lori wipe, iranlọwọ mi si ẹlẹha na yori si rere".

Ọba si tun bere lọwọ rẹ wipe, "njẹ ko yẹ ki Ẹlẹha na fun ọ ni nkan nipa iranlọwọ ti o ṣe fun un yi?'

Baba na si dahun wipe, "emi ko gbọdọ ni ireti fun kinikan nipa eyi nitoripe, Ọlọrun nikan na n'o le mọ igbẹhin ohunkohun.

"Boya o le ṣẹlẹ ni ọjọ miran wipe, ki ọkan ninu awọn aromọdọmọ ẹlẹha yi jẹ ẹniti yio ṣe aromọdọmọ temi na ni oore ti o ju eyi lọ lẹhin-ọla. Nitorina, ko si ẹtọ kankan fun mi lati reti wipe, boya, o yẹ ki ngba ohunkohun lọwọ ẹlẹha yi nipa ore ti mo ṣe fun un o."

### ỌBA PAṢẸ

Lẹhin eyi ni ọba na wa paṣẹ wipe ki wọn lọ pe iya ẹlẹha na ati awọn ọmọ rẹ wa si iwaju on, nwọn si ṣe bẹ ẹ. Ọba si bere lọwọ iya ẹlẹha yi wipe, bawo ni ọrọ yi ti jẹ larin iya Ẹlẹha na pelu baba-onikẹkẹ.

Iya na si sọ wipe, baba na jẹ enia rere fun on to bẹ ẹ ti on ko le gbagbe oore rẹ titi aiye, atipe, nipa oore rẹ na ni on ti bẹrẹsi iṣe irohin fun awọn ọmọ on lati ijẹta to bẹ ẹ ti awọn ọmọ on paapa fi gba adura wipe ki Ọlọrun ṣe awọn ni ẹniti yio le san diẹ ninu oore nla yi pada.

Ọba na si tun bere wipe, "Njẹ ẹnyin ati Baba yi ko ti mọ ara nyin tẹlẹri?" Iya Ẹlẹha na si sọ wipe, "emi ko tilẹ ba a pade ri laiye yi".

Olotu, ki a tun fi rere pade o. O digba.

## Owe ilẹ Yoruba

Nwọn ni oju npọn enia, iwọ ni ko mọ ore, bi o ba mọ ore, kini yio fi san an ?

Jamba ta fun jamba ra, oni-kankan-keke p a d e alawagun-wagun.

Eerun (Ijalọ) ki i ja ki o pa iya okete, bi o kanran ki o pa a, iya okete yio binu jade ọsan ni.

(Wo oju ewe keje)

**tete gun RUDGE debẹ lasiko**




Bẹni, iwọ yio ma a tete de nigbagbogbo bi o ba ni basikulu Rudge kan. Ko si irin mọ, ko si iduro fun awọn mọto ti nwọn to di ọna mọ—Ki o si ṣe iranti pe—o ko ni sanwo epo-mọto fun lilo. Rudge nitoripe basikulu Rudge yio ni alopẹ fun ọ titi aiye.

Yan iru Rudge tirẹ loni ki o si ma a gbadun ogo ati ominira ti o ni lori wipe, o ni basikulu ti o yara julọ loju ọna.

JOHN HOLT NI O NTA A KAKIRI YIKA GBOGBO NAIJIRIA

# SHONIBARẸ JẸ OYE AṢIWAJU IJẸBU-ODE



AWORAN yi ni ti igbati Ọba Sikiru Adetona, Ogbagba ... Keji, Awujale Ijebu-Ode [illegible]





AWORAN yi ni ti igbati Ọba Sikiru Adetona, Awujale Ijebu Ode ati awọn Oloye ... (VIP Rest House) ni Ijebu Ode [illegible]

* * *

CEGBE [illegible] Shonibare [illegible] Ijebu-Ode [illegible] Oloye A. O. Shonibare [illegible] Oloye A. O. Okunowo Olisa Ijebu-Ode.





## Owe I ę Yoruba

[illegible]


*Fif'ojusi ìgba iwaju!*

Ọpọlọpọ ile iṣẹ titun titun yio wà lara awọn anfani ti Nigeria yio ni niwaju.

Awọn ile iṣẹ titun titun ti

THE UNITED AFRICA COMPANY

dasilẹ funra wọn ni Iwọ-Õrun

Africa *lẹ ni ogõn*, eyiti afi

nṣe atilẹhin itẹsiwaju orilẹde yi.

[illegible]


*Ẹ ma a ka Iwe*

IROHIN YORUBA

*nigbagbogbo fun irohin aladun*


Taji loju oorun

Ki o si ṣ'ara giri!

Pelu

ANDREWS LIVER SALT



[illegible]

ANDREWS YIO RAN O LOWO LATI TUN DI ARAFUN SI ONA META

[illegible]

LABO ... ANDREWS LIVER SALT FUN IFIO ... FUN OKUN ARA

# K'ALARA SUNRAKI

## Lati ọwọ "OMI ATA"

# Fun isọkan Naijiria (2)

**Ọmọ Kekere: Isọkan**
**Agbalagba; isọkan;**
**Ẹ jẹ k'a dibo fun isọkan.**

ENYIN ọmọluwabi, mo ki nyin, ẹ jire o,

Ẹ ku ijakadi pẹlu ọran aiye,

Ẹ ku gboke-gbodo pẹlu ati jẹun ọtọtọ ọran!

Edumare a siju anu wo wa,

Ebi ko ni pa wa ta olori-aṣọ wa jẹun,

A ko ni tori ipo gbe orilẹ-ede wa sọnu.

Mo tun de bi mo ti nde pẹlu iregbe mi,

Ẹ jọwọ f'inudidun ba mi jomitoro ọrọ pataki.

Ọrọ mi ti bẹrẹ, o si mbẹ lori IṢỌKAN,

Ani AṢỌKAN NAIJIRIA.

Gbogbo nyin ki ẹ tẹtileri ki ẹ ma gbọ,

Ọran isọkan ilu ṣoro,

O dabi ọran isọkan Ọlọrun pẹlu enia.

Isọkan?

Tani nsọrọ sango laisi agbo girisa?

Tani nfẹ isọkan lai ti ilẹkun mọ iwa aibikita?

Ṣe ẹ ngbọ ọrọ mi lagbọye,

Ikanisi ni olotu irẹpọ,

Irẹpọ ni onfa to nfa ajumọse,

Ajumọse ni mu isọkan dun;

Ẹniti ko kanisi ko fẹ irẹpọ pẹlu ẹni,

Laisi irẹpọ, ajumọse ko le bọsi rara,

Iyẹn ko le wọ:

Bi mo ba fajuro si ọ, ọrẹ,

Iwọ ko ni rẹrin si mi;

Bi mo ba f'ikorira pe ọ, ara,

Iwọ ko ni f'ifẹ da mi lohun.

Bu ọla fun mi, ki emi bu ọla fun ọ,

Pe mi lenia, ki emi se ọ l'ọba;

Ọwọ fun ẹdun ọkan mi,

Ijuba Ọlọrun ninu ilosi mi pẹlu rẹ;

Ero ati ọrọ rẹ ko pami lara,

Iṣesi mi si ọ jẹ bi mo ti fẹ ki iwọ se simi;

Ibaniwi pẹlu ifẹ, nigbati a ba yẹ fun ibawi,

Ibanidamọran pẹlu ododo, nigbati a ba fẹ imọran.

Awọn wọnyi le mu enia wa ni isọkan pẹlu ara wọn.

Mo wi, isọkan ko le si ninu ikorira ati iwa abuku enia.

**Ọmọde ilu, anikanjẹ,**
**Agba ilu, anikanjẹ,**
**Olowo ilu, anikanjẹ;**
**Ọlọgbọn ilu, anikanjẹ,**
**K'emi jẹ, k'iwọ ma gbọdọ jẹ,**
**Isọkan lodi s'anikanjẹ.**

Ọrọ mi ti siwaju, o ti lọ sẹhin,

Ṣugbọn o duro ṣinṣin lori isọkan, agbara orilẹ-ede.

Mo ti fi owe sọrọ, mo si rope o ye dede wa, pe

**Keta, inunibini, ikorira ati abuku,**

**Anikanjẹ ati igberasanlẹ-igberaga,**

**Ko le jogun ire isọkan lọdọ enia.**

Ẹnyin oṣelu, ki ẹ ma gbọ,

Bi ẹnyin ba fẹ isọkan Naijiria nitotọ,

Bi ẹnyin ba fẹ alafia ati ilọsiwaju Naijiria ninu ominira,

Ẹ dakun, mo bẹ nyin,
Ẹ fiyesi ọrọ ẹnu,
Ẹ jọwọ toju iwa.

Ọrọ ti mo ti gbọ lẹnu awọn oṣelu jomi loju,

Iwa ti mo ti ri ti nwọn hu, dẹruba mi pọ;

Bi enia kan ba wọ ẹwu abuku s'ijoye ati ọba,

Bioluwarẹ ba de fila "kele gbe ọ" si awọn ẹya kan,

Ti o nrin irin "Tani yio mu mi" lori ẹdun ọkan enia,

Jọwọ, maṣe sọ fun mi pe iyẹn nfẹ isọkan Naijiria,

Oju ko fẹ'ra ku o!

# Alufa Samuel Awẹ bẹ Olotu wo

EKO:

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu ti o kọja yi ni Ẹni-Ọwọ Alufa Samuel Awẹ ti iṣe alamojuto Ijọ Church Army of Africa" Ilesha wa ṣe ibẹwo Olotu Iwe Irohin Yoruba. Inu Olotu si dun si i lati gba a ni alejo.

Lẹhin ti nwọn yọ ki ara wọn tan ni ojiṣẹ Ọlọrun na wa ṣe alaye bi awọn irohin, itan, ati orisirisi ọrọ ti o njade ninu Iwe Irohin Yoruba ti nfi imọlẹ gbogbo nkan ti nlọ ni Naijiria han gbogbo aiye si.

Olotu wa bere pe oruko Ijọ rẹ yi ṣe ajeji si on, ati pe on ko ro pe Ijọ na wa ni ilẹ yi. Alufa na ṣe alaye wipe ki i ṣe Ijọ ti a ṣẹṣẹ da silẹ, o ti wa pẹ, o ni kakiri Naijiria ni awọn ni ẹka, ẹka awọn si wa ni Eko yi paapa (Mushin).

O si tun sọ siwaju pe awọn alufa Ijọ na a ma a kiri ojule gbadura f'awọn arugbo ati awọn ọmọ alainibaba ati fun awọn alaisan kakiri awọn ile iwosan ati ni ile iwosan University College Ibadan, ati pe Ijọ awọn pẹlu ibẹwo ti on wa ṣe l'Eko. Alufa Ọlaliwẹ ni alamojuto Ijọ ti Mushin na.

Lẹhin ti on pẹlu Olotu fi ọrọ jomitoro fun igba diẹ tan ni o ba dagbere fun un pe o digba o ṣe o, ipade wa bi oyin o.


# Mu OVALTINE lojojumọ!



Mu OVALTINE larọ fun agbara jalẹ gbogbo ọjọ.

Mu OVALTINE sun lalẹ lati fi ara rẹ si eto nigbati o ba sun.



**OVALTINE — Onjẹ Atata — ti o jẹ nkan Mimu**

# AGBAYANU IROHIN ALAGBARA! NWỌN NTA COMET RADIO NI G.B.O.! RADIO TO NLO BATIRI TABI TRANSISTỌ NI WỌN OHUM WỌN LAGBARA PUPO NWỌNSI NSỌRỌ KETEKETE ATIPE. OWO PỌKU NI NWỌN NTA WỌN




**Tetisi awọn irohin ati are oloyimọmọ lori Comet Radio**

**E.C.500**
O lagbara Transistọ mẹsan
Are-Radio lati orisi ọna mẹta
Apoti rẹ ndan daradara
O ni aworan ẹrọ rẹ lara
£6-10-0

**NT 10D**
Radio to nlo batiri ati fabu
Ti ogublọgọ enia to mọ nipa radio fẹran
Apoti to ndan yinrinyinrin
Are-radio lorisi ọna meji
£13-10-0

**Comet**
**RADIO SETS**

G.B.O. TECHNICAL SERVICE DEPARTMENT

Awọn ọsiṣẹ-ẹrọ radio G.B.O. se radio
yi lati sọrọ dada nigbagbogbo
Aimọ to ba pẹ o le fẹ ki nwọn o yẹ
radio rẹ wo G.B.O. yio ṣe
eyi fun ọ lowo pọku

**LATI**
# GBO

G. B. OLLIVANT (NIGERIA) LTD

# Obirin kan ni ọran ọkọ on ọmọ Ẹgbẹ Olomi su on

ILỌRIN.

LENULỌLỌYI ni Iyaafin Jinahi Arinọla Bakare sọ fun Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ Ilọrin pe ọran ọkọ on, Ọgbẹni Sunmọla Bakare su on pata-pata, on si fẹ lati kọ ọ silẹ patapata. O ni lati igbati ọkọ on ti fi Ẹgbẹ Ilọrin Talaka Parapọ dapọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre silẹ wọ'nu Ẹgbẹ Olomi (NPC) ni ko ti si idunnu ati irẹpọ larin awọn. O si ṣe alaye pe awọn obi ọkọ on ati awọn obi on ti nwọn jẹ ọmọ Ẹgbẹ Ilọrin Talaka Parapọ dapọ mọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ko ni idunnu si awọn mọ nitori Ẹgbẹ Olomi ti ọkọ on lọ ṣe.

Arinọla si tun sọ fun Adajọ pe ọkọ on ba awọn ọmọ Ẹgbẹ Olomi polowo ibo lọ Bussa ninu oṣu ti o koja yi. O ni ọsẹ mẹta ni o si ba wọn ṣe nibẹ ṣugbọn ṣile mẹtala pere ni o gba wale. O si ni, ninu ogi ni awọn wa, awọn ko gbadun rara.

Ọkọ rẹ, Ọgbẹni Sunmọla Bakare si sọ fun Adajọ pe on ṣi ni ifẹ rẹ gidigidi, on ko si fẹ ki o kọ on silẹ. O si ni ki Adajọ ba on rọ aya on na ki o ma kọ on silẹ. Adajọ si dajọ pe ki obirin na lọ da ponun mẹtadinlọgorin ṣile mẹfa ati kobo mẹjọ (£77 6s. 8d.) owo ifẹ pada fun ọkọ rẹ.

## IDAHUN SI IBERE AWỌN AJẸ

OLOTU, ẹ jọwọ gba mi laye ki nfi esi si ibere Ọgbẹni Ajakaiye Ogun ti Wasinmi, nipa awọn Ajẹ, eyiti o jade ninu iwe "Irohin Yoruba" ti ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu kẹta ọdun yi. Ibere rẹ na ni pe: "Ewo ni irọ, ewo si ni otitọ ninu ọrọ ti Omidan Lydia Ọlatundun sọ ati eyiti Iyaafin Elizabeth Ọmọlade tun sọ?"

Omidan Ọlatundun sọ pe ẹiyẹ ni ajẹ, ẹmi ni ajẹ . . . " Iyaafin Ọmọlade si ti sọ pe "ajẹ ki iṣe ẹiyẹ." Idahun temi ni pe ọrọ awọn mejeji na fẹ gbigbe yẹwo, nwọn gbiyanju.

Gbogbo wa la mọ pe agbara ajẹ pọ, ko si si ibiti nwọn ti le mu enia, tabi ki nwọn ba ti enia jẹ. Agbara aiye yi wa ni ọwọ wọn. Ọlọrun nikan loju wọn lọ.

Ohun ti mo fẹ fayọ nipe ẹmi ni ajẹ. Ẹmi enia ni nwọn fi ngba ẹiyẹ. Mo fẹ ki ẹnyin onkawe iwe "Irohin Yoruba" ti ibikan kiyesi ọrọ mi yi: ti enia na ni ẹmi Eṣu ninu, oluwarẹ ko ni ni ẹmi Idariji si ọmọ ẹnikeji rẹ. Awọn ti nwọn ba ni iru Ẹmi Eṣu bayi yio jẹ ole, ọlọṣa ati apania.

Iru awọn ti nwọn ni Ẹmi Eṣu bayi ni nwọn nṣe oṣo, awọn ni nwọn nfi ẹmi enia wa owo kakiri, nwọn ko sile ni isinmi titi ọjọ aiye wọn. Ẹmi Eṣu lo sun wọn de ibẹ.

Lakotan, idahun temi nipe Ẹmi ni nṣe Ajẹ o, ki i ṣe ẹiyẹ o.

Emi ni,

S. O. OYETUNBI.

Ibini (Benin City)

## Alapara Ibadan

Lati oju ewe keji

OLOTU—Ṣugbọn oju wọn ti la nisisiyi ju ti igbati o nwi yẹn lọ. Ṣe awọn enia tiwa ti la wọn loju, nipa ijiya ti Ẹgbẹ Olomi NPC) nfun wọn, ti nwọn mbo wọn ni ilagba ni idi, ti wọn ba mu oti yo.

ALAPARA—Ọran ko dun gbọrọ ni wọn, bi o ba ṣe ẹ ni arọ, a tun yọ lalẹ, nwọn iba bo "Baakodaya" ni ogoji ilagba tan nisisiyi, bi ẹ ba ti gbe tuwọ silẹ fun un pe ki o jẹ, o ti gbagbe iya rẹ.

OLOTU—Awọn Eka Ẹgbẹ Afẹnifẹre wa lọhun ti nwọn nfi han wọn pe iya ni Ẹgbẹ Olomi (NPC) fi nje wọn, awọn paapa si ngburo iru alafia ati idẹra ti awọn enia Ipinlẹ Iwo-Orun fi nṣe ayọ nipa eto iṣelu Ijọba na ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre nṣe akoso rẹ.

ALAPARA—Awọn ti ẹ nwi wonyi ni awọn ti o ti ri iriri nipa iṣẹ ribiribi ti awọn Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ṣe si Ipinlẹ Iwo-Orun ni ẹ nwi yẹn, ti nwọn si je alatilẹhin Ẹgbẹ Afẹnfẹre. Awọn bi "kannike, bi Buusu, bi Sọsọ ati bẹẹ bẹẹ lọ ti nwọn lo sua, ti nwọn po bi yanrin eti okun, ti nwọn ko si gbọ ohun ti aiye nwi, a fi tuwo tabi "fura-da-nunu".

OLOTU—Iyẹn ni pe o ko lọ woran idibo na mọ?

ALAPARA—Nda o, eniti a nwo ki i woran mo ti fẹ oko mi si ito. Ẹ jọwọ ojẹ nkan mi mo fẹ de ibikan naa. Bi a ba ti gburo ayorid idibo na, a o ma a sọ iọsẹ ti mbọ. O digba oṣe o.

OLOTU—Ma a wolẹ o, oju ko fẹra ku o.



Mama fun mi ni

AMAMA

ni ojojumọ

AMAMA

O NJẸKI NGNI AGBARA ATI ILERA

NI NAIJIRIA NI A TI ṢE AMAMA

AWỌN ALAGBATA RẸ NI: GLAXO—ALLENBURYS (NIGERIA) LTD, P. M. B, 2310, LAGOS, ati pẹlu ni ABA ati KANO.

### SHỌNIBARẸ DUPẸ LỌWỌ AWỌN ALABAṢẸYẸ IWUYE

**OLOYE S. O. SHỌNIBARẸ**
(Asiwaju Ijẹbu-Ode)
ati
**OLOYE (IYAAFIN) A. O. SHONIBARẸ**
(Ọtunba Mojibade Ijẹbu-Ode)

dupẹ lọwọ gbogbo awọn ẹniti nwọn fi waya abẹ omi, waya oke, ati lẹta ranṣẹ si wọn, ti nwọn fi ki wọn ku-orire, ati gbogbo awọn ti nwọn pilẹ wa si ibi aṣeyẹ oye ti

**ỌBA ALAIYELUWA AWUJALẸ**
(Ijẹbu-Ode)

fi da wọn lọla, ati gbogbo awọn ẹniti o fi ẹbun-owo ati ifẹ-inu-rere ranṣẹ si wọn nigbati nwọn nṣe inawo aṣeyẹ iwuye wọn na.

No. 68

### *Correspondence On Pension Matters*

It is notified for general information that the former Pensions Section of the Ministry of Finance has now been integrated with the Pensions Branch of the Ministry of Establishments. In future all correspondence on any aspect of pensions matters should be addressed to:

THE PERMANENT SECRETARY,
Ministry of Establishments,
(Pensions & Gratuities Branch)
Lagos.

NO correspondence should be addressed to the Accountant-General of the Federation and copying of correspondence to that office should cease forthwith.

Published by Allied newspapers Limited, Elephant House 214, Broad Street, Lagos and printed for them by Amalgamated Press of Nigeria Limited, 5/7, Apongbon Street, Lagos. Fun owo 'IROHIN YORUBA' odun kan EKO sile mejo ati kobo mejo (8/8d) Ilu miran ni Nigeria ati Oke-Okun sile metala (13s) Olotu S. M. Ademuyiwa 2, Idumagbo Street, Odi-Olowo, Mushin.